Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sin Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kla L'oja o ta.

ELETI OFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fiwe y… ṣ e ikede si awọn aṣoju iwe irohin Eleti Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, ẹnikẹni ti ko ba fi owo ti o ti lẹ ranṣẹ si wa, ao pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si ẹnibẹ mọ.

VOL. XI No. 626. LAGOS, SATURDAY, MAY 30—JUNE 5, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Ilu Gba Omoba Ati Iyafin Re L'alejo, Eko Mititi !

Ọlọla Oloye Duke ti ilu Gloucester, ẹgbọn fun Ọba Obinrin ilu Oyinbo na ni a nwo aworan rẹ ti o ngbọwọ lọwọ ọkan ninu awọn Emir tilu Kastina, Ọba ilẹ Oke-Ọya, nigbati o fi mba wọn ṣe ajọyọ ominira Ariwa n i l e Hausa.

Nigbati Alaiyeluwa ọba Adele Keji lọ pade alejo ọmọba ilu Oyinbo to de, o mu ọpa rẹ dani lọ. Nigbati ọmọba na ki ọba Adele tan, o gba ọpa ọwọ rẹ, o si yẹwo. Ẹnu ya lati ri iru ọpa bẹ ni gbẹgbẹlẹ yi.

Lẹhin Ọba, ẹniti o tun lọ ki ọmọba ni Dokita Ọlatunji Adeniyi Jones, Olotu ilera ilu. Ọgbẹni M. Bank Anthony ati Lande, iyawo rẹ.

Diẹ ninu awọn enia ti ọmọba na tun ki ni Bishop J. K. R. Aggey, Alhaji, Y. P. O. Shodeinde a t i Alhaja rẹ, Oloye Ashogbon, Oloye Faji ati Erelu.

Ọgbeni S.B Dabiri Olori awon Scouts in Ọmọba f i ami i y i n (Medal) mimo riri iṣẹ rẹ da lola bakanna lo tun fi ami (Medal) mimo iyi iṣẹ ti o ṣe da Major Amodu Katsina lo'la.

O si lẹ mọ wọn ni igbaiya awọn ero iworan patewọ fun wọn, awọn si ba wọn yọ.

IYAWO DUKE GBADUN ERE AWỌN ỌMỌBINRIN

Awọn ẹgbẹ ọdọmọbinrin ti a npe ni Girl Guides n'nu ọgba ile Gomina Agba nilu Eko ni Oloye Duchess ti ilu Gloucester ti iṣe iyawo Duke ni o fi ọwọ re ṣere loju ilu ti omidan Kufeji n l u nibiti awọn ti njo ijo ibilẹ fi han iyawo Duke na.

Ere wọn na jọ Oloye Duchess loju pupọ depo ti on paapa fi fi ọwọ ṣere loju ilu wọn nigbati o ndun yungba.



THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Througo·t Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E.Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## E Foju Sona

IWE IROHIN ELETI - OFẸ

YIO BERẸ SI KỌ IROHIN LEDE HAUSA FUN ANFANI AWỌN OPỌ ENIA TI O NKA IWE WA YI.

YIO BẸRẸ LOSẸ TI O MBỌ YI LAGBARA EDUMARE .

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### Coal Handling Plant

Tenders are invited for the purchase of Coal Handling Plant at present located at the Abeokuta Power Station.

The specifications of this plant are as follows:

(a) Lenght of ropeway ,, ,, ,, 513 yards
(b) Carrying capacity ,, ,, ,, 2 1/2 tons
(c) Buckets (size 2'3" x 1'10 1/2" x 1'5" depth) 10 No.
(d) Average ground clearance ,, ,, 17'6"
(e) Towers ,, ,, ,, ,, 6 No.
(f) Spacing of towers ,, ,, ,, 85'
(g) Plant driven by 3HP motor and driving gear in good condition

On payment of a deposit of £5 at the Electricity Corporation of Nigeria Headquarters, 13, Broad Street, Lagos, or to the Engineer and Manager, Abeokuta, arrangments will be made for inspection of the Coal Handling Plant.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential Tender for Coal Handling Plant" and must be received at the Office of :-

The Secretary,
Electicity Corporation of Nigeria,
Electicity Headquarters,
13 Broad Street,
Private Mail Bag 2030,
Lagos.

not later than noon on Saturday, 6th June, 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

On receipt of a bona fide tender, the deposit of £5 will be refunded. The Electricity Corporation of Nigeria does n o t undertake to accept the lowest or any tender.

**ARTHUR FAUL**
Secretary to the Corporation

# Duke Lo Be Ilu Pakistan Wo



Ẹniti a nwo ti o duro lowo osi ni **Prince Phillip, oko oba**, eniti o lo be ilu **India** ati **Pakistan** wo, o de **Burma Singapore Sarawak Brunei, North Borneo, Hong Kong** ati opolopo awon ilu be ki o to pada **si ilu London** ni ojo **30th osu April 1959.**

### IPADE OSU KETA-KETA AJO BABALAWO AGBAIYE.

Ipade ọjọ meji ti oṣu Ketaketa ti Ajọ Babalawo agbaiye, ni ae se ni ilu IKORODU, n i ile Araba IKORODU, ni ọjẹ Aje (7th a t i 8th) ọ j ọ Keje ati ọjọ Kejọ ọṣu OKUDU ti Odunni.

awọn i k ọ lati ayika agbaiye ni nwọn yio wa si ipade yi.

Gbadebo Dosumu
Akọwe Gbogbo-gbo
Ajo Babalawo Agbaiye.

### FUBORA FẸ BINU KU

SURULERE Ọkunrin kan ti o njẹ Fubora ni o ro aropin ara rẹ wipe aiye yi tilẹ su on. Ọkunrin na ti o njẹ Fubora kowe si iya, awọn ọrẹ rẹ, baba rẹ ati ẹniti o duro fun ni kotu wipe, bi o ba jẹ wipe, ki a pa ara ẹni ni ipin ti Ọlorun yan fun on, on ti fi ara mo bẹ.

Ọlọpa sọ fun adajọ wipe lẹhin ti Fubora kọwe yi tan, lo wa lo egbogi ti o njẹki enia sun o gbe meii rẹ mi, lẹhin na lo wa berẹ si ṣe aisan ki nwọn to tete gbe lo si ile alaisan.

Nwọn fi sun ẹsun pe o fẹ binu pa ara rẹ o si jẹbi ẹsun na. Adajọ wo o titi, o si ṣanu rẹ o ṣe ikilọ fun o si da silẹ.


## E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

LỌSỌSẸ, O KUN FUN IROHIN ALADUN




## Hogan Bassey Ngbaradi Fun Ija-atunja



Larapa ija idanrawo ti Ogbeni Davey Moore ba Hogan "Kid" Bassey ja ninu eyiti nwon ni lati da ija na duro nitoripe Bassey ti fi ara sese. Ija na ni nwọn ngbero lati tunja nilu Los Angeles lọjọ 19th oṣu August 1959

Lẹniti a nwo ninu aworan yi Ogbẹni Hogan Bassey nibiti o ti ndanrawo nipa iru ija ti yio ba Davey Moore ja lọjọ na. Ogbeni George Biddle ti o jẹ oluṣọkọ Bassey sọ wipe Bassey yio ti de ilu Los Angeles niwon oṣu kan ki ọjọ ija na to pe. ki afẹfẹ ibẹ le ba laramu.

Kere o !

**Ati ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.**

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
**7 Egerton Road Lagos**

## Akowe Agba Ilu Amerika D'ologbe

AMERIKA. Ogbeni John Foster Dulles, ti iṣe Sekiteri agba fun ilẹ Amerika ni agbo wipe o ti oju-orun de oju iku ni irọwọ-rọṣẹ ninu ile Iwosan awọn Ologun ti a npe ni Walter Reed Army Hospital nibi ti o ti wa labe itọju fun arun buburu kan ti awọn Dokita npe ni Cancer.

Arun buburu yi ni a gbọ wipe o ti mba ọkunrin na ja lati igbati o ti de ile Iwosan yi, sugbọn nigbati irora ti arun na nfun pọ ni awọn ba jẹki o ma sun ki o le ri irorun sugbon Oluwa wipe asiko to, ni ọjọjọ fi de ba lọju orun.

Ogbeni Dulles ku, o fi iyawo ati ọmọ meji sile pelu arakunrin ati arabinrin re.

## JAMBA MOTO ṢẸLẸ LONA KATSINA

KADUNA. A gbọ wipe adọta awọn obinrin ni Oba Katsina fi ranṣẹ si ilu Kaduna lati pelu awọn obinrin ti yio se onje fun awọn ọkunrin ti yio gun ẹṣin ni be ere Durbar.

Ere Durbar pari tan ni awọn obinrin na npada lọ si ilu wọn lojiji ni moto na fori sọgi, o si pa Malama Gọsi Bisi ati Aminatu Ṣata awọn obinrin yoku bi iwọn ogun enia fi ara ṣeṣe.

A si tun gbọ irohin lati Kaduna wipe, ẹgba a marun le ni ẹdẹgbẹrin enia (10,700) lo ba wọn gun ẹṣin ni be ere Durbar. Onjẹ ti awọn enia na jẹ fun iba ọsẹ meji ti nwọn fi wa ni Kaduna jẹ ọdanrun malu.

## OFINKO MỌẸNI-ỌWỌ

ADO EKITI. O ta siwa leti ẹnrẹn wipe awọn ọlọpa ti fi Olọye Ekiti kan sun esun pe o pora owo bi ogofa poun ninu Igbimọ ibilẹ.

Awọn ọlọpa wipe lati igbati o ti gba pe on jebi esun na, ko iti da owo na pada sinu apo Igbimọ lati igbati o ti gba owo na lọwọ awọn ti o nsanwo ori ninu osu December to koja, lẹhinti nwon ti rante lo to ṣeṣe wa se bẹ. Adajọ fi si awọn ọjọ kan.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

38, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 62. SATURDAY MAY 30 - JUNE 5, 1959


## E Wa Wo o o.

Ohun ti a ba jowo ni o ngun, ni gbolohun ti o jade lẹnu wa nigbati Ọlọla Akowe Agba Ogbẹni Lennox-Boyd ti ilu Oyinbo pe ipade awọn Olotu ijọba wa ati awọn isọngbe wọn pẹlu Gomina Agba ti gbogbo ilẹ Nigeria ati awọn Gomina ipinlẹ mẹrẹrin, ti Iwọ orun Ila-orun, Ariwa ati Gusu, ilẹ Kamarun, lati ṣe ijiroro pọ nipa bi o ti ṣe eto ti gbogbo iṣẹ ti ao ṣe ki a to le gba Ominira gbogbo-gbo fun ilẹ Nigeria yi to bọ si rọwọrọsẹ fun tẹru-t'ọmọ yika gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki ipade na to pari ni Akọwe Agba, Ọgbẹni Lennox-Boyd sọ fun awọn aṣiwaju oṣelu wa wipe ninu oṣu July ti o mbọ yi ni ao tẹ gbogbo awọn eto alafia ati igbadun ti y o wa ninu eto iṣelu Ominira wa, nipa ọrọ siso tabi ipade ṣiṣe yika gbogbo ilẹ Nigeria.

Eyi dun mọ wa ninu pupọ nitoripe nwọn igbati awọn aṣiwaju wa ti f'ohun sọkan lori ijọba alafi ati igbadun, adura tiwa ni ki Oluwa Olodumare alanujulọ re ṣe iranlọwọ fun wọn ki nwọn le mu ọrọ ajọsọ wọn yi duro ṣinṣin.

Akọwe Agba na, Ọgbẹni Lennox-Boyd ati iyawo re dakan lọ bẹ ilu Ibadan wo lọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu May, ki o to pada wa ri Olotu ijọba ilu Kamarun nilu Eko, ni ọjọ kejidinlọgbọn, lẹhinna ni o wa re kọja lọ silu Saro ati Gambia ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu May yi.

Ohun ti a ba jọro l'o ngun.




# Sardauna Nlo Si Meka



KADUNA Irohin kan wa lara lati ilu Kaduna wipe, Alhaji Sir Ahmadu Bello, ti o jẹ aṣiwaju awọn oṣelu nilẹ Hausa ti nmura, o si ngbaradi lati lọ ba wọn ṣe Hadji lọdun ni.

Eyi ni yio di igba ẹkarun ti Sardauna mba wọn ṣe Hadji. Barika rẹ, oke Arafa ti o gun, barika rẹ.

## ỌMỌ ILẸ HAUSA GBADUN KERENI APAPA

APAPA Awọn Olotu Ports Authority lo gba alejo nla kan ti o wa lati ile Hausa wa fi oju ri iru iṣẹ to nwon ṣe silu Eko. Alejo na ni Seriki Abudu Rahaman Gabir ọmọ Dan-fodio Olori ilu Isa ni agbegbe Sokoto.

Ọmọ ẹwu gẹgẹbi Ọba, ọpọlọpọ oyinbo ati enia dudu si tẹle lẹhin. Nigbati o nworan titi ti o de ile ẹru karun, ẹnu ya lati ri owu ti o ti agbegbe ọdọ rẹ wa o duro nibẹ, o si nworan bi ẹrọ ẹpingun ido ti ngbe ẹru lo, gbe ẹru bọ.

Nigbati o de Atlantic Terminal o rin yi ẹka ori kereni na, o fi ẹsẹ rin lọ lori kereni titi o fi de ibi ti ọkọ oyinbo Palm line kan wa, o wọ inu rẹ wo lati ri gẹgẹbi ọkọ oyinbo tiri. Nwon mu lọ sile ẹrọ ti o ngbe ọkọ na rin nwon si mu lọ si Down Below inu rẹ dun si gbogbo ohun ti o ri. Nigbati ilẹ nsu lọ lo ba wọ ọkọ igbaja (Launch) ti nwọn si mu gunlẹ si Eko.

# Pope Gba Awon Alufa Ilu Nigeria Meji Lalejo.

VATICAN. A gbo irohin pe awon alufa ti ijo Aguda meji ti nwon rin ẹirin ajo mimo lo si ilu Rome lati lo fi oju kan Pope Mimo. Oruko awon aririn 'oju - meji na ni Monsignor Joseph Whelan ti o je Bishop fun ijo Aguda ilu Owerri, ẹeni keji ni Monsignor Richard Finn ti o je Bishop ile Ibadan.




## Awon Akogun Ba Olopa Fa Ijogbon

ABẸOKUTA. Awọn gende ọkunrin meji ti nwọn fi ẹfun, ati osun kun oju ati ara ni adajọ kotu Ake ṣa konko Pọun mẹdọgbọn mọ lara ni sisan tabi bẹkọ ki nwọn lọ si ẹwọn oṣu mẹta.

Bi a ti gbo ti ọrọ na lọ niyi, awọn Akogun ọkunrin meji nwọnyi ba Ṣaji ọlọpa ja lẹnu iṣẹ rẹ, nwọn si ṣe ọkunrin kan ti o njẹ Karimu Ọlọnọde leṣe.

Agbọ wipe awọn Akogun mejeji na jẹ ara Itoko ati pe nwọn mbẹ ninu ago Akogun yi nigbati jamba na ṣelẹ. Oruko awọn mejeji Aremu Ayinla ati Kushimọ Ọdẹjọbi.

## OWO OLOPA TE OLORI AWON OLOSA ILE KALABA

UYO. Awọn ọlọpa ti a fi ṣe atipo si agbegbe ilu Uyo, lọna ilẹ Kalabа fi ye wa pe, ọwọ awọn ti tẹ meji ninu awọn olori Olọsa ti o ma nfigba gbogbo dana ko enia lẹru.

Nigbati awọn ọlọsa nwọnyi ba dena ti nwọn si mu ẹnikan, nwon o wi fun oluwarẹ pe, 'Amauke' itumo eyi ni wipe owo lo fẹ tabi emi rẹ. Awọn ọlọpa si ti ndẹ ọdẹ wọn ti nwọn ko ri wọn mu.

Ninu oṣu April, owo olopa tẹ okan ninu awon olori Ọlọṣa na ti o njẹ Nkutikut. Nwon ti koko mu olori won kan ri. Oruko oga olopa ti o mu won ni Inspector Okon.

Awon olopa ba ṣe ẹjọ nilu Uyo, nwon si fi suu opolopo ẹsun Ọlọṣa won ba ibon llewo (Revolver) kan lowo rẹ.

Ogunlọgọ awon enia lo mu ẹsun wa wipe dukia won sonu, kẹkẹ basikulu won sonu tabi pe nwon ji işu won wa ni ọna aroko gbogbo. Ẹniti nwọn ri mu na ni adajọ fi si ẹwọn ọdun mẹsan.

## Fi Ese Kan Pa Meje

(Apa II)

Lati Owo ESO

Bi Afese pa meje ti nkoja le rigbore, apegba ni gbogbo enia mo ope e, on na a si ma da won lohun wipe Ho o, e gbere e. Ni ojo kan, a rona wipe a file gbo wipe gbogbo awon enia ope on ni afese pa meje, o to ki on se nkan ki gbogbo aiye fi le mo wipe on to oruko na je.

O d'de o mu ciye kan sinu apo o si tun mu kanriakan Oyinbo, o ki bo omi, o ja si apo lo ba bere irin ajo re o rin lo sinu igbo, inno egan, odun ati aginju, ebi bere si pa a o fi buredi je bota, o wa fi ehin ti igi Ose lo ba sun lo.

Bi Omiran kan nti apada lo sile, beni o gborun eran enia, o bere si wo lie lotun ati losi titi o fi kan Afisepa meje, o ka oruko ara beliti re, o wipe' eh ehen! ekunrin na ti a ti ngbo okiki re niyi, lo ba gbe si ejika o koti sile. Aiya Afesepa-meje ja nigba to ba ara re ni oferefe, oyara mu apo ti o nkowo pamo si, o fi korun.

Nigbati o de, o so o kale o mu sibi meji, o mu okun fun Afesepa-meje, o ni ki o wa ma eko, awon mejeji si jo njeun lo. Bi o ba ri pe Omiran na ko wo on mo, yio da eko na sinu apo aiya re, beni lo si nse titi nwon fi jeun tan. Afese pa meje wa dide, o rin, o ayan niwaju Omiran na, o wa bere l o w o re pe iwo ko ha gboro mi ri si ndan ? ohun ti mo ba se Iwo ko le se, Omiran na dahun pe, Ko si ohun ti iwo yio se ti emi kolese Afesepa meje fi obe to apo ti o ti nda eko si, eko ina re dana. Fuya ti Omiran dide o le ohe bo agbede ara re, o si ku.

O kiki Afesepa meje bere si kan.

(koiti par.)

## Ayinike Ati Ayinipada

(Apa V)

Lati Owo Eso

Gegebi aye ti a ba itan wa de, Ajapa da obo ni aduyoke, iwara-papa wa mu gbogbo awon omo eranko wipe, haba ! Ajapa ewe ti o ma npa gologolo nibin, alapa ni ngo fi se loni.

Ni wara nsesa Ijakumo bo s'ode fun Ajapa, kawi, kafo, lo ba fi egandi le Ajapa o gbe e o so o soke, ki o to dele Ajapa ni Ayinike, Gbi ! ni Ijakumo dun nile.

Ajapa da gbogbo awon Susawere tan, o wa ku awon ijoye nina eranko. Nigbana ni Ajapa wa darin bayi pe

Gir-r-r- gba gidigbo, Heya
Ija yi kan agbagba
Aiye o, kan agbagba.

Erinmado bo s'ode ariwo ta gee, wipe, o ya ti Ajapa yio ku wayi. Laifa oro gun awon mejeji woya iya ija ko ju iwon seju marun lo ni Erinmado gbe Ajapa roke rodo, o fe fi ibinu laa pa, Ajapa dahun pe Ayinike! beni Erinmado subu inle Ajapa si duro le lori.

Bayi ni Ajapa da gbogbo awon eranko were ati eran nlanla, bi Ajanaku, Egbin, Efon. Gidigidi, Aroni, Ira, Ekiri. Agbalangbo Kiniun Imado, Turuku, Inaki Ijimere ati gbogbo awon eranko,

Nwon wa so fun Ajapa wipe ko ti la gbogbo eranko tan, o si ku Ologbo. Ajapa dahun pe on ko gbaregbe dani bi Ologbo ba fe ki o jade si agbo.

Ologbo bere lowo Ajapa wipe kini ohun ti o wi ? Ajapa dahun pe bi o ba fe ki o jade si agbo ni mo wi. Oro yi ba Ologbo ninu je to be ti o fi ko lori ba Ajapa ja.

E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe eo ma gbo bi Ologbo tise la Ajapa mole ni ose to mbo.

### A Toro Gafara

Loju ewe keji iwe wa Ose tokoja ni a fi aworan Ogbeni Adisa Williams si ti a pe ni "Igi lehin Ogba egbe Olope" ati pe "O fi lu Ibadan se ibugbe nisiiyi"-eyi ko je be, Ogbeni A. Williams mbe nilu Oyinbo nisisiyi. Asiko ni eyi, e se gafara.

Olotu.

## Iwadi Iku Oremule

IBADAN. Ogbeni D. A. Oremile ti o je akowe Adajo ni a gbo wipe o lo sibi apeje kan ni ojo Atalata, dide ti o dele ni o di eni ti nwon ndu se n ajo fun ki nwon to gbe lo si ile Iwosan ti University, ko si pe lehin ti o de ibe tan lo koja lo sibi isinmi aiyeraiye.

Friday 22nd osu May 1959 lojo ti nwon fi iwadi na si. Sugbon ni gba ti iyawo re to je o l o r i a w o n eleri ti Ijoba ko si nile, ko jeki nwon le se iwadi oro na. Iyawo na, gegebi a ti gbo, o lo si Ijeru fun ti oku oko re.

A bi Ogbeni Oremule ni o'o 11th osu September 1914, o si pari emi re kuro laiye n i ojo 19th osu May 1959.

O bere ise labe ijoba ni odun 1935, diedie l o nsun siwaju, titi ki o to wa di akowe Kotu adajo agba ni odun 1956.

## AWON OMO DA ROCHA FE GBA DIE NINU OGUN BABA WON

EKO. A gbo irohin wipe awon omo Ologbe Candido Da Rocha se iwe lo siwaju adajo wipe awon Loya ti nwon gba sidi edekoye ti o sele larapa ogun ti baba won fi sile, nfe owo, be ni ko si si owo lowo won. nitorina, ki adajo gba won laye lati gba die ninu owo baba won ti o mbe ninu Bank.

Adajo si gba fun won, sugbon nwon koiti se ipinnu lori iye owo ti nwon ma gba. Adajo so fun asoju pe, iyekiye ti awon Babansinku ba gba ninu dukia na ki o se isiro re mo ogun Da Rocha.

E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE

LOSOSE, O KUN FUN IROHIN ALADUN

NO. /5008/2/2

## Unified Local Government Service
## PUBLIC NOTICE
### VACANCY FOR ENGINEERING ASSISTANT

Applications are invited from suitably qualified persons for appointment to fill the vacant post of an Engineering Assistant in the Unified Local Government Service.

Scale of Salary : Scale C(T) 1,2,(408 x 18 - £462 x 24 - £510) (£570 x 24 - £618, £690 x 24 - £744)

Qualifications : Applicants must possess the Diploma of Yaba Technical Institute in Building and Engineering or its equivalent.

Dutis : The successful applicant will be posted to the office of a Town Engineer to work in and immediately around the town concerned.

Method of Application : Applications should be made on forms obtainable from the Secretary, Local Government Service Board, Agodi Ibadan, or from the Official Secretary, 26 Grosvenor Gardens, London, S.W.1.

Application forms of candidates in Local Government Service should be submitted through the Secretary of the Council concerned and the Local Government Adviser. Application forms from candidates in Government Service should be submitted through the applicants' Head of Department, and be accompanied by a confindential report on the prescribed form.

Applications should be addressed to the Secretary, Local Government Service Board, Ibadan, so as to reach him not later than the 14th of June, 1959. For candidates in the United Kingdom applications should be addressed to the Official Secretary, to reach him not later than the 7th of June.

## Ore Igba Iponju Ni Ore Ododo

Olotu,

Lai ṣe iyemeji. mo dupẹ lọwọ Malama Inanusa, Iya ẹgbẹ awọn obinrin ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Oke-Ọya, fun ọrọ rẹ ti o fi ta awọn ọmọ ẹgbẹ N.E.P.U. ji wipe ki nwon wa sowopo pẹlu ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) lati gb'ogun ti Ipọnju. Irẹwẹsi, Idena fun alafia, Ifiyajẹni ati Iwa keta ti o gbilẹ nilẹ Hausa.

Fun opolopo odun ti awọn omo ẹgbẹ N.E.P.U. ti njiya lowo ẹgbẹ (N.P.C.) ti opolopo won, l'okunrin. l'obinrin ti f'ara ṣe ẹwọn nipa oro siso tabi ikede to lodi si adaṣe ijoba Oke-Ọya. Nwon ti jẹ won niya nina logorin ẹgba tabi jubẹlo larin oja fun ese ti ko nilari.

Gbogbo asiko ti a fi inba won s'ejo ti a fi njẹ won niya wonyi, ẹgbẹ Alakuko (N.C.N.C) ti o jẹ alabaṣepo egbẹ N.E.P.U yi fi gbigbo ṣe alaigbo, nwon si ko N.E.P.U silẹ pe ki nwon nikan ma jiya won. Awon egbẹ Alakuko ko fi igba kan ba awon alabaṣepo won dasi oro iya elẹta-elero ti awon ẹgbẹ Olomi (N.P.C.) fi njẹ won na.

Awon nkan wonyi ni ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ri, ti anu si ṣe won niwon ba fi lọ ba won lati ṣe iranlowo fun won. Lati igbana ni nwon ti nṣe gudugudu meje lati fi alafia awon enia mulẹ nilẹ Oke-ọya. Nwon ko loya kun be lati ma gba awon ọmọ ẹgbẹ won silẹ ati awon alabaṣepo won ki ijoba alafia le fidi mule nile Oke-ọya.

Ẹyi nikan kọ, ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) tun tesiwaju nipa fifi ye awon enia ilẹ Hausa wipe "Ohun ti o ba dara fun Sardauna o yẹ ki o dara fun Malam Mọmọdu pẹlu", ati pe ohun ti o ba dara fun Oloye Awolọwọ, yẹ ki o dara fun Malam bakanna. Eyi ni ẹgbẹ Action Group se wipe "Ominira fun gbogbo wa, idẹra fun gbogbo enia".

Ko si igba kan ti ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) fi ṣe eto lati gba awon ọmọ ẹgbẹ won tabi alabaṣepapọ won ninu wahala iwa ifi kẹta jẹnia niya ri, eyi ni ohun ti awon enia pataki ṣe fi egbẹ na silẹ awon ẹni bi Malam Ibrahim Immam, Uthman Jaa ati awon bẹbẹ. A ma ngbo wipe ẹsin funfun dara l'agbo" ni oju ti awon enia fi nwo N.E.P.U. sugbon anu se ni wipe ẹsin funfun kori ẹnire gun ti yio fi gbawaju ninu ere ije kan.

Asiko to nisisiyi fun egbe N. E. P. U. lati mo wipe ẹgbẹ N. C. N. C. ki iṣe ọrẹ igba iponju ki si ṣe ọrẹ ododo fun won. Nitorina, mo pelu Malama Inanusa kesi enyin omo egbe N.E.P.U. wibe ki ẹfi owọ sowọpọ pelu Action Group gb'ogun ti Iponju Irewesi, Idena alafia ati Iwa ifiketa jeni niya ti ijọba Oke-Oya nlo lori nyin.

Ao tun ṣe itumọ iwe yi l'edẹ Hausa ti a bere enitì yio ba wa te jade.

Emi ni,
B. A. Carew
A. G. Secretary.






## Nwon Se Eye Fun Omoba (Duke) Nilu Eko

EKO. Ni ọjọ Wednesday 27th oṣu ni Ọmọba (Duke of Gloucester) ba ọkọ ofurufu gunle si idi ọkọ ofurufu ni Ikẹja awon ọlọpa si to lati (Round about) ni Yaba lọtun ati losi, lẹhin na awon ṣoja tun to lotun ati losi, lehin na awon Scouts to lotunlosi titi lo fi wọ ile Gomina nilu Eko.

Ni ojọ Alamisi 28th osu May 1959 nwon agogo mejọ owurọ awon ero ti peju peṣẹ si gbalasa ọdan lati yẹ ọmọba na si, awon ṣoja 1st Battalion ati awon ọmọ ogun oju omi tile Nigeria (Navy) ati awon Ọlọpa, lo parapọ lati yẹ omoba (Duke) na si awon onifere ti olopa lo lulu fun won jo lẹjọ na.

Ibi ijoko ti Prince of Wales ati ti Grand Stand ni ijoba fi silẹ fun awon Minister, awon ijimi enia ati Councillors lati joko. Gbogbo awonenia ti ko mu iwe ipe dani, nwon ko jẹki nwon wole, sugbon nwon gba won ni aye lati duro sibikan ni sale, gbogbo awon enia ti ko ri aye lo woran leti si ẹrọ redio.

## Ole Fo Ile Adura Ni Mushin

**IKẸJA. Ọkunrin kan ti o njẹ Braimo Alabi Oniṣowo l'o pe ara rẹ, ni a gbọ wipe o wọ ile Adura ẹgbẹ awọn Serafu lọ ni Mushin, o si ko wọn ni aṣọ adura. Gbogbo dukia ti o ri ko ninu ile adura na to £31 - 2s.**

Ile adura awọn Serafu ti o mbẹ ni Coker Street, ni nwọn fọ ni ọjọ 4th oṣu April, 1959, adajọ si yẹ ọjọ igbẹjọ na si ọjọ 6th oṣu June, 1959.

## O[illegible] TO JA NI M[illegible]ṢALAṢI W'ẸWỌN

EKO. Irohin kan wa wipe okunrin agbalagba kan, ti o si je gbajumo lo wo inu Mosalasi Okepopo lo, o si lo ka itẹ (Carpet) titun ti nwon sese ra ni Poun mewa ti nwon te sile. oruko agbalagba ole na nje Bello Alabi.

Nigbati owo te ole na, nwon fa a fun adajo ni Kotu Tapa Teṣon, adajo si paṣẹ pe ki o lo si ẹwọn oṣu mejila.

## OBA LEOPOLD TI NWON RO LOYE FẸ JA-DE NI AFIN

BRUSSELS. Irohin de eti gbo wa wipe awon igbimo ilu Belgium ṣe ikede lehin ipade kankanṣi kan ti nwon se wipe Oba Leopold ti a ti ro loye so wipe on yio kuro l'Afin ti Laeken, ibiti on ati ọmọ re, Baudouin, ti o j'oba ti jijọ ngbe.

Laipe ni nwon fi Oba ana yi sun ẹsun pe o ndasi ọrọ ilu. Wiwa ni Afin rẹ pelu iyawo rẹ keji ko le rogbo, o le je pe eyi ni ko jẹ ki Oba Baudouin gbeyawo.

Ero awon Oselu ni pe bi Oba ana, Leopold ba jade nile, yio jeki Oba Baudouin kekere le yi iwa pada lati ọdun kejọ to ti jọba.

## Alarinkiri De-waju Adajo

KALABAR. Ọkunrin kan John Okokon ni awọn ọlọpa mu duro niwaju adajọ fun esun wipe o nrin - gba-nraye kiri tobẹ ti o fi wọ ile Bishop ijọ Aguda lọ, o si lọ joko lori ijoko rẹ, o fe si ori rẹ, o gbe ẹsẹ le ẹse, eyi ni oro to ṣẹlẹ larin adajo ati Okokon.

Adajo-Kini iwọ lọ wa ninu ile Bishop ?
Okokon-Mo lo gbadura ni.
Ada-Ṣe ti iwo ko kuku lo si orun lo gbadura ?
Oko-Nio mo ona orun, iwo ko mo ona Ṣosi
Oko-Mo ti Ṣoko gbadura ninu Ṣosi mo wa lo tari rẹ ninu ile Bishop.
Ada-Bawo lo ti se wa lo fẹ sori aga Bishop.
Oko-Enia sa ni lati joko bi o ba enia lalejo.

Adajo so wipe awọn Dokita ti so pe ori rẹ pe, ko si si amodi kankan lara rẹ, ṣugbọn emi ro wipe nkan mbẹ lara rẹ, nitorina mo fi eyi fa ọ leti ki o ma lọ o ko gbọdọ tun ṣe bẹ mọ

## Okunrin Kan Ko Iyawo Re Sile Nitori Iran-wiwo.

YABA. Ọkunrin kan wi fun iyawo rẹ pe, on fẹ jẹun, ko bu onjẹ fun on. Obinrin na ti se iresi silẹ fun ọkọ re yi, bi o si ti gburo pe ọba mbọ pe ! ni obinrin na gbe onjẹ ọkọ rẹ ju silẹ ti o si bẹ sita o sare lọ woran ọba ti o mbọ.

Ocre ti obinrin na sare lọ woran tan ni ọkọ rẹ bọ sidi iṣasun o si jeun yo tan ni iyawo rẹ ba wọle ọkọ obinrin na ko ẹgbẹ ti iyawo yi. Gegebi iyawo na ti je alajangbila to, nigbogbo asiko ti oko re fi nna ni ẹgba, ko sa rara, beni ko mira titi ti ọkọ na fi te ifẹ re lọrun.

Awọn aladugbo si bere si wipe ha ! enia lo na to yi ? Lehin ti inu oko re rele tan ni inu ṣeṣẹ wa bi Iyawo, o fa apola igi yọ o na mọ ọkọ re ni itan ese o si ye, ni nwon ba gbe lọ si Othopaedic Hospital. Nigbati ọkọ na pada de lo ba le iyawo rẹ lọ.

## AWỌN ADAJỌ TITUN ṢẸṢẸ DE

Ijọba apapọṣe tilu Eko ti fi aṣẹ si yiyan awọn enia wọnyi si ipo adajo. Ninu won ni obinrin kan wa oruko rẹ ni Iyafin C.O. Okunuga- Oruko awọn yoku ni Ọgbeni J.A Ọlaloye, S.B. Keshinro ati S. Atake.

Ẹniti a daruko gbẹhin yi ti bere iṣe lati inu oṣu May 1959. Ṣugbọn awọn yoku ti bere nipari oṣu February 1959

## Oloye Awolowo Gba'lejo



IBADAN. Oloye Duke ati Iyafin re be ilu Ibadan wo l'ana ọjọ Jimọ ti a le pe ni "Jimọ Oloyin" bi ede ilu Ọyọ, fun didun ti ilu Ibadan dun nigbati alejo nla na de, ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, ti iṣe Olotu ijoba Iwo - Orun, t'ẹwọ ifẹ gba.

### ORIN EKO

**Mo de 'le Ado, mo de Ijebu-Ode, emi mọ Imẹsi-Olọja, otitọ wọn** ṣ'ọwọn o, bo' ba le purọ wa yo, ṣugbọn l'Eko o, bo o ba le seke se wa jẹun.

Lati Ọwọ
Mọmodu Kokoro.


ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN [illegible] ... ọra [illegible] ... Nitori [illegible] awọn Yoruba [illegible] ni "ATA", Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BORỌKỌNIT". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. [illegible] Ṣegemant ni.

The Egba Trading Arada̱n Stores,
13 Denton Bridge St., P. O. Box 2, Ebute-Metta.





Printed & published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370